# ILANA OLORUN TI O RỌRUN Nipa Igbala

Ọrẹ mi ọwọn, mo mbẹrẹ ibere ti o pataki julọ ninu igbesi aiye. Ayọ tabi ibinujẹ rẹ titi aiyeraiye duro lori rẹ Ibere na si ni: Njẹ a ha ti gba ọ la? Ki iṣe bi o ti dara to, Ṣugbọn, a ha ti gba ọ la? Ki iṣe boya o jẹ ọmọ lẹhin ijọ kan, Ṣugbọn, a ha ti gba ọ la? Ko si ẹnikan ti o le gbadun ẹkun rẹrẹ ibukun Ọlọrun tabi ki o wọ ijọba Ọlọrun lai ti ri igbala. Jesu wi fun Nikodemu ninu Johannu 3:7 "A KO LE ṢE ALAITUN NYIN BI." Ọlọrun fun wa ninu ọrọ Rẹ ilana KAṢOṢO fun igbala. Ilann na rọrun, a le gba ọ la LONI. Ekini, iwọ ọrẹ ni, o nilati mọ wipe ẸLẸṢẸ NI IWỌ NṢE.

Romu 3:10 – "Ko si ẹniti iṣe olododo, ko si ẹnikan." Romu 3:22, 23 – "Nitori ko si iyatọ: GBOGBO ENIA li os a ti ṣẹ, ti nwọn si kuna Ogo Ọlọrun."

KO SI AYE fun ọ lati ri igbala biko ṣe pe o gba wipe ẹlẹṣẹ ni iwọ nṣe. Nitoripe ẹlẹṣẹ ti iwọ nṣe ati da ẸJỌ IKU fun ọ. Romu 6:23 – "Nitori iku li ere ẹṣẹ." Jakọbu 1:15 – "Ẹṣẹ, a bi iku."

Eyini jẹ iyakuro lọdọ Ọlọrun, ninu ỌRUN APADI, TITI LAI. Bi o ti buru to, Bẹni iwọ ọrẹ mi, otitọ si ni Ama Ọlọrun fẹran rẹ to bẹ gẹ, ti o FI ỌMỌ BIBI RẸ KANṢO-ṢO. Jesu Kristi, ṣe ARỌPO rẹ, ẹniti o ru ẹṣẹ RẸ ti o si ku rọpo RẸ.

II Korinti 5:21 — "Nitori o fi I (Jesu) ṣe ẸṢẸ nitori WA, ẹniti ko mọ ẹṣẹkẹṣẹ ri, ki AWA LE Dl ODODO Ọlọrun ninu RẸ."

I Peteru 2:24 — "Ẹniti on T1KARARẸ fi ara Rẹ ru ẹṣẹ WA lori igi, pe ki AWA ki o le di oku si ẹṣẹ ki a si da aye si ododo: nipa ina ẹniti A MU NYIN LARADA."

Ko le ye wa lẹsẹkanna bi Jesu ti ru ẹṣẹ wa, ama Ọlọrun sọ wipe BẸNI ninu ỌRỌ RẸ.

Iwọ Ọrẹ mi, ẹṣẹ re nitorina a ti gbe e le Jesu ẹnito o ku rọpo RẸ. Otitọ ni, Ọlọrun ki nṣe eke.

Oga onitubu ti ilu Filippi bere lọwọ Paulu on Sila; wipe kini ki EMI ki o ṢE ki NG le LA?

Iṣe Awọn Aposteli 16:31 – "Nwọn si wi fun u pe, GBA Jesu Kristi Oluwa wa GBỌ, A O SI GBA Ọ LA, IWỌ ati awọn ara ile rẹ pẹlu."

Sa gba A gbọ pe o ru ẸṢẸ RẸ ti o si ku RỌPO RẸ Nisisiyi, kepe E.

Romu 10:13 – "Nitori ẸNIKẸNI ti o ba sa pe orukọ. Oluwa, Li a o gbala."

A fun wa ni aduia fun ẹlẹṣẹ ninu iwe Luku 18:13 – "Ọlọrun ṣanu FUN MI, EMI ẸLẸṢẸ."

Nisisiy ẹlẹṣẹ ni iwọ nṣe o si ṣe ọ lanu nitorina Nibikibi ti a ba le wa nisisiyi gbe ọkan rẹ soke ninu adura si Ọlọrun Ko gba akoko ti o pọ, nitoripe Ọlọrun Nkọju lati gba ọ la.

Sa wipe. Oluwa ẹlẹṣẹ li emi nṣe o ṣe mi lanu, Ṣanu fun mi, ki o si Gba mi La nitori Jesu Sa gba a gẹgẹbi ọrọ RẸ ti wi.

Romu 10:13 — "Nitori ẸNIKẸNI (Iwo jẹ ok an ninu nwọn) ti o ba sa pe orukọ Oluwa, LI A O GBALA, LI A O, ki nṣe boya a le gba a la. ṣugbọn) LI A O GBALA."

Sa gba A gẹgẹbi Ọrọ Rẹ Bi o ba ti se ohun ti o wi fun ọ, TẸWỌGBA IGBALA RẸ NIPA IGBAGBO, gẹgẹbi ỌRỌ RẸ. Gbagbọ a o gba ọ la Ko si ijọ, ko si ẹgbẹ, ko si isẹ rere, ko si elomiran lẹhin jesu ti ole gba ọ la.

Ilana igbala ti orun li: ẸLẸṢẸ NI IWỌ NSE; nitorina o NILAT ku tabi ki o gba Kristi bi arọpo rẹ ti o ku fun ọ. Sa pe orukọ Rẹ, ni mimọ pe ẹlẹṣẹ li iwọ nṣe ki o si tọrọ fun anu Rẹ, ki o si gba Ọ NITORI JESU.

Sa gba a gẹgẹbi Ọrọ Rẹ, Nipa Igbagbp, Gba Igbala. O le wipe "njẹ ohun gbogbo ti mo ni lati ṣe ha tan bi." Bẹni, ko ju bẹ lọ. A dupẹ lọwọ Ọlọrun pe ọpọlọpọ ti ri igbala nipa ilana yi. Ilana Ọlọrun ni ti Bibeli si ni Pẹlu. Iwọ ọrẹ mi. Gba a Gbọ ki o si tẹle e Loni Nisisiyi li akoko na - Loni li ọjọ na.

II Korinti 6:2 – “Kiyesi i. Nisisiyi ni akoko itẹwọgba kiyesi i, Nisisiyi ni ọjọ igbala.”
Owe 27:1 – “Maṣe leri ara rẹ niti ọjọ, ọla, nitoriti iwọ ko mọ ohun ti ọjọ kan yio hu jade.”

Bi ko ba ye ọ to ka a, ki o si TUN KA A titi yi o fi ye ọ. Maṣe kọ iwe kekere yi silẹ a fi ti o ba ye ọ. ẸMI RẸ ju gbogbo ọrọ aiye lọ.

Marku 8:36. 37 – “Nitoripe ere kini fun enia bi o ba jere gbogbo aiye, ti o si sọ ẸMI RẸ nu? Tabi kili enia iba fi ṣe paṣiparọ ẸMI RẸ?”

Mọ daju pe a ti gba ọ la Ju ohun gbogbo lọ o nfẹ igbala. Bi o ba sọ Ẹmi Rẹ nu O Padanu Ọrun ati Ohun gbogbo. Ọlọrun Ran Ọ Lọwọ Lati Ri Igbala Loni.

I Korinti 10:13 – “Ko si, idanwo kan ti o ti ba nyin, bikoṣe iru eyi ti o mọ niwọn fun enia: Ṣugbọn olododo li Ọlọrun, ẹniti ko yio jẹ ki a da nyin wo ju bi ẹnyin ti le gba; Ṣugbọn ti yio si ṣe ọna atiyọ pẹlu ninu idanwo na; ki ẹnyin ki o ba le gba a.”

MAṢE gbẹkẹle ero rẹ KA BIBELI RẸ-Ọlọrun mba ọ sọrọ. MA JẸRI-Iwọ sọrọ fun Ọlọrun.
Matteu 10 : 32 — “Nitorina ẹnikẹni ti o ba jẹwọ mi niwaju enia, on li emi o jẹwọ pẹlu ni waju Baba mi ti mbẹ li ọrun.”

Bi o ba ri igbala, kowe simi ngo si ba ọ yọ.

Lati Owo: FORD PORTER
Copyright: Lifegate Inc., 2007
192